Ko si akoran, ko si si ifi ẹyẹ fura mọ daadaa tabi aburu, ati pe mo fẹ́ràn fah'lu, o sọ pe wọn sọ pe: Kí ni fah'lu? O sọ pe: "Ọrọ ti o daa

Lati ọdọ Anas ọmọ Maalik- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: "Ko si akoran, ko si si ifi ẹyẹ fura mọ daadaa tabi aburu, ati pe mo fẹ́ràn fah'lu, o sọ pe wọn sọ pe: Kí ni fah'lu? O sọ pe: "Ọrọ ti o daa".
[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe dajudaju akoran ti èèyàn asiko aimọkan ni adisọkan rẹ pe dajudaju aisan maa n ṣi kuro fun ara rẹ bọ si ara ẹlomiran láìṣe pẹlu kadara Ọlọhun jẹ ibajẹ, Ati pe ifi ẹyẹ fura mọ daadaa tabi aburu jẹ ibajẹ, oun ni ifuramọ aburu lati ara èyíkéyìí nnkan ti a gbọ́ lo jẹ ni tabi ti a ri, ninu awọn ẹyẹ tabi awọn ẹranko tabi awọn oni ailera tabi awọn onka tabi awọn ọjọ tabi eyi ti o yàtọ̀ si wọn, Wọn dárúkọ awọn ẹyẹ nitori pe o jẹ eyi ti o gbajumọ lọdọ awọn ara asiko aimọkan, ati pe ipilẹ rẹ ni titu ẹyẹ silẹ nigba ti a ba fẹ bẹ̀rẹ̀ iṣẹ kan bii irin-ajo tabi owo tabi eyi ti o yàtọ̀ si ìyẹn, ti o ba fo lọ si ẹgbẹ ọtun, ó maa furamọ daadaa, o si maa ba nnkan ti o fẹ lọ, ti o ba fo lọ si ẹgbẹ òsì, o maa furamọ aburu, o si maa koraro kuro nibi nnkan ti o fẹ. Lẹyin naa, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe dajudaju ọrọ daadaa maa n wu òun, oun ni nnkan ti o maa n ṣẹlẹ̀ si ọmọniyan bii ayọ̀ ati idunnu ninu ọrọ daadaa ti o n gbọ́, ti o si maa mu ro ero daadaa pẹlu Olúwa rẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3422